# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 898 LAGOS SATURDAY DEC. 7 — DECEMBER 13 1963 KỌBỌ MEJI (2D)

Kinni Eleyi o?

# Awon Agba Oselu Meji Yinbo.ı Pa Ara Won Ninu Ile Igbimo

BRAZIL—Bayi ni a nṣe ni ile wa, ewọ ibomiran ni ọrọ awọn agba oṣelu ara ilu Brazil ni ilu awọn Aguda ti nwọn fi ibon ilewọ meji yanju ọrọ funra wọn ni ijẹta nigbati nwọn nṣe ipade lọwọ, ti ọkan ninu wọn si ku bamubamu. Orukọ awọn agba oṣelu mejeji na ni Arnon De Mello ati Silvester Monteiro.

A gbọ wipe ọta ni awọn mejeji ti nba ara wọn ṣe lati ọdun mọdun, Ọta wọn na pọ tobẹgẹ ti awọn mejeji pẹlu awọn ọmọ wọn ati aya wọn ki fi ba ara wọn sọrọ rara.

Onirohin wa ni agba oṣelu Monteiro ni o nsọrọ lọwọ ninu ile aṣofin na; a ko mọ nkan ti o wi ti o bi De Mello ninu ti o fi fa ibọn ilewọ (Revolver) yọ ti o bẹrẹsi yin in si Monteiro nibiti o gbe duro si sọrọ.

A gbọ wipe Monteiro alara paapa fa ibọn tirẹ na yọ ti on na bẹrẹsi yin in si ọta rẹ, nibiti nwọn gbe ti nyin ibọn wọnyi ni ọta lọ ba oṣelu agba kan ti o njẹ Jose Cairan ti o si pa a bamubamu.

Awọn Ọlọpa ilu Brazil na si ti mu awọn baba onibọn mejeji na ṣugbọn awọn alakoso ilu na ti pe gbogbo awọn aṣoju ilu si ipade nla kan ti nwọn fẹ ṣe ninu ile Igbimọ aṣofin lati ro nkan ti nwọn yio ṣe lori ọrọ awọn baba oṣelu ti nwọn yinbọn pa enia ninu ile igbimọ na.

## Baba Onihoteli Pe Dairo Olorin Lejo pe On Ni Ko Sere Fun

EKO — Ẹjọ kan pataki ti adajọ kotu awọn ọlọpa ni Eko yio ṣe ki a to ṣe odun Keresimesi ni ti baba oni hotẹli kan, Ogbẹni E. A. Ajayi ti Wayfarers ni Popo Aguda pe akọrinta kan, Ọgbeni I K. Dairo fun adehun ti nwọn jọ ṣe wipe ki Dairo wa lu'lu fun awọn onibara on.

Gẹgẹbi iwe ẹjọ ti nwọn ha fun Ọgbẹni Dairo nibiti o gbe nlu ilu fun awọn kan ni jo ni Mokọla ni Ibadan ni ana Ọgbeni Ajayi ni ton pẹlu je fọwọ bọ iwe adehun kan nigbakan ninu ọdun yi wipe ki o kọ awọn ọmọlere rẹ wa ṣere fun on, Ajayi ni Dairo ko wa rara.

Baba oni hotẹli na ni on fẹ ki adajọ ba on gba irinwo pọnun o le medogun (£415) lọwọ Dairo fun akọrinta na fun wahala ti o ko on si. Ajayi tun ṣe alaye ninu iwe ipẹjọ rẹ na wipe ki adajọ ṣa igi mọ akọrin na lori wipe o paṣẹ fun un wipe ki ọ ma tun huwa irufẹ bẹ mọ ati wipe ko gbọdọ ṣe ere ni ibomiran ninu ọdun Keresimesi ati ọdun titun, a fi ni inu ọgba hotẹli on l'Eko.

Lọjọ mẹwa loni ni nwọn yio beresi ro ẹjọ na ninu kotu igbẹjọ awọn ọlọpa l'Eko.

## Nwon Ju Obinrin Pansaga Ti O Jeki Nwon So Minisita Sewon Osu Mesan

LONDON — Obinrin ọdọmọde kan Christine Keeler ti nwọn titori ọrọ rẹ yọ minisita John Profomo lẹnu iṣẹ ni a gbọ wipe adajọ kotu nla kan

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

Awon Aguda Da Awon Tisa Duro

## Pope Mimo Nlo Gbadura Loju Orori Jesu

ROME Irohin ti tan kakiri gbogbo agbaiye wipe ninu oṣu ti mbọ (oṣu kini ninu ọdun titun) ni Ẹnọwọ Pope Paul yio rin irin-ajo lọ si Jerusalẹmu lati lọ gbadura ki alafia le wa lori ilẹ aiye.

Ni ijẹta ni PAPA MIMỌ nṣe ikede irin ajo ti o fẹ rin na fun ogunlọgọ awọn Biṣobu agba ọmọ ijọ rẹ ti nwọn wa sibi ipade nla kan ti nwọn ṣe ni Saint Peter.

A gbọ wipe Papa Mimọ ni wahala pọ ninu aiye tobẹgẹ ti o fi yẹ ki gbogbo awọn onigbagbọ ododo gba awẹ, ki nwọn si tun gbadura ki rogbodiyan le kuro ninu aiye. PAPA MIMỌ paapa ni on a de gbogbo ibi mimọ ti o wa ni ilu Jerusalemu ti nwọn ti bi Jesu Krisiti, on a si gbadura fun gbogbo awọn araiye ki irẹpọ le wa, ki awọn alagbara aiye yẹ mura ija ogun lojojumọ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Awon Olopa Nse Iwadi Bawo Ni Iwe Idanwo Se Han Sita

IJEBU - ODE Ọpọlọpọ awọn Ọtẹlẹmuyẹ awọn Ọlọpa ni wọn ti wọ ilu yi lati ọjọ mẹta wa lori irọ kẹke irohin iwe-idanwo ti nwọn ṣe ni bọn'kẹle lati fi dan awọn ọmọ ilewe ti nwọn fẹ pari ẹkọ wọn wo ti iwe idanwo na si ti han sita.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Awon Ara Ilu Gesi Da'wo Fun Dokita Alanu

**BIRMINGHAM** — Dokita alanu kan ti o nfi ọkọ ofurufu (aeroplane) sare kiri inu igbo Oke Ọya ni ilu awọn Hausa, ti orukọ rẹ njẹ Dokita Neil Duncan ni a gbọ wipe awọn ara ilu Gẹsi da owo gọbọyi kan fun wipe ki o le ri nkan ma lo fun iṣẹ anu ti o nṣe kiri larin awọn Hausa.

A gbọ wipe dokita oniṣegun na ti bẹrẹ iṣẹ anu ṣiṣe yi ti pẹ ni ibẹrẹ ọdun ni, ki ategun nla kan to ba ọkọ ofurufu ti o fi nṣe ẹṣẹ rin jẹ, eyi ba lọkan jẹ pupọ, ni ilu Oyinbo lọdọ awọn alanu ilu Gẹsi wipe ki nwọn ko ran on lọwọ.

Onirohin wa ọpọlọpọ awọn enia ni nwọn dide ti nwọn da owo nilewe ile iṣẹ Ṣọṣi ati ile ẹgbẹ fun on. Nwọn ti ri ẹgba mẹdọgbọn pọnu (£50,000) ko fun oniṣegun na wipe ki o si lọ fi ra gbogbo nkan ti yio ba ra fun ilọsiwajn iṣẹ iṣẹ anu ti o nṣe kiri na. Nwọn si tun nda owo fun un lọwọ bayi.

A tun gbọ wipe awọn ilu Gẹsi ti nwọn nṣe aapọn da owo na ni awọn ni lati ri wipe gbogbo ọkẹ mẹrin pọnun (£80000) ni awọn a da tan laipẹ adọjọ ti a npe ni ep[illegible]ni.

## Onirohin Agbaiye Pe Onise Pulu Lejo

EKO — Irohin kan ti a tun ri gbọ lọdọ akọwe onirohin wa kan ni ti awọn Onirohin agbaiye (REUTERS LIMITED ti nwọn pe awọn ẹgbẹ kan, Pan African Pools, ti nwọn ṣe iṣẹ pulu lẹjọ fun gbese iṣẹ ti nwọn se fun wọn ti nwọn ko sanwo fun wọn.

Koru-ganran ni awọn Oyinbo onirohin agbaiye pe ẹjọ na si, awọn ni ẹgbẹta o le ogoji pọnun (£640) ni iṣẹ ti awọn ṣe fun awọn oniṣẹpulu na larin oṣu mẹsan

A gbọ wipe niwaju adajọagba Ọgbẹni G.B.A. Coker ni awọn yio ti se ẹjọ na ninu oṣu ti o bẹrẹ ọdun titun ti a fẹ bẹrẹ yi.

# Awon Onise Pulu Pade Agbako Ni Ibadan

IBADAN — Ọpọlọpọ ile iṣẹ pulu, ti nwọn nfi oribande bọlu ṣe iṣẹ tẹtẹ-tita (fixed Odds) ni Ibadan ati agbegbe rẹ ni nwọn paṣẹ wipe ki awọn ọlọpa ti bamuba nu nitoripe ọpọlọpọ wọn ni nwọn ko ni iwe-aṣẹ lati maṣe iṣẹ na.

Alamojuto eto aje Ọba C.D. Akran ṣe alaye fun awọn akọwe oniwe irohin wipe wahala ti awọn oniṣe pulu na nfun awọn ti pọ ju, ojojumọ ni nwọn nmu ẹsun wọn wa sọdọ awọn wipe awọn jẹ owo lọdọ wọn ṣugbọn nwọn ko ni owo lati san fun nwọn.

Ọba Akran ni ki awọn to gba ẹnikan laye lati ma ṣe iṣẹ na ni ilẹ ikibi ni Ipinlẹ Iwọ Orun, o ni lati ko Ọkẹ kan o le ẹdẹgbajọ pọnun (£35,000) ṣarai wa duro lọdọ awọn.

Ni ọsẹ ti o koja lọbun ọpọlọpọ awọn ara Ibadan ati ni aroko ni nwọn ṣe orire pulu ti nwọn ra, ṣugbọn ọpọlọpọ awọn oniṣẹ pulu na ni nwọn fẹsẹ fẹ ẹ, ti nwọn sa lọ fara pamọ nigbati nwọn ko ri owo san fun awọn onibara wọn.

**Plushes Velvet Velveteen Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, Faji Market

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

## RETURN OF THANKS

Hadji Rasaki Bakare Alobọh on behalf of himself and the entire members of his family hereby return thanks to all those who by personal calls, telegrams and otherwise sympathised with them for the loss they sustained by the death of their beloved father, Gbadamosi Arolahun the Olori of Egbe Ilupeju, which sad event took place on November 17th 1963.

Hadji Rasaki Bakare (Alọbọ)

E Ka

**Iwe Irohin Eleti - Ofe**

**Ti O kun Fun Irohin aladun Losose**

### Olofintoto Ni:

# Se Alabosi Ni Awon Yoruba ...?

Bi ko ba si iwe kan ti mo ri gba ninu ọsẹ yi lọwọ Ọgbẹni wa kan ti o pe ara rẹ ni ALHERI ỌMỌ HAUSA, emi ko ba ti tete fẹnu kan ọrọ Alabosi koṣe Alabosi ti nwọn ni awọn aṣiwaju wa ni ile Yoruba nṣe.

Bi alabosi ba wa, bi ko ba si, ẹ jẹki a sa ti ni suru, ki a mọ woye, ki a mọ ibiti gbogbo ọrọ awa ọmọ-ku-arẹ jire yio yọri si ninu eyiti a bọ si yi, Ṣugbọn mo fẹ ki ẹ ba mi foju kan wo iwe-wasika na ti mo ri gba lati ọdọ ALHERI ỌMỌ HAUSA ti o fi ṣọwọ si Olotu Eleti-Ọfẹ, ti Olotu na gbe fun mi wipe boya o le wulo fun mi.

## Iwa Abosi

O ya, iwe na niyi, ẹ ma-ka a nisọ: "Olotu mo re wipe ẹ ko gbagbe ọrọ ti mo sọ ninu iwe ti mo kọ si yin ninu ọdun ti o kọja wipe awa Hausa kiṣe ọdalẹ ati alabosi enia rara. Mo ni gbogbo nkan ti o de si awọn Yoruba, awọn funra wọn ni nwọn fọwọ ara wọn fa a.

"Awọn Yoruba na ni nwọn pa owe kan bayi wipe Alufa sọrọ, ojo ku, o ni Ọlọrun ni o jẹri si ọrọ on-iyẹn ni gbolohun ọrọ ti awọn ikọ ti nwọn wa si ipade-ajọ nla ti awọn ẹgbẹ Afẹnifere (AG) ṣe ni Ibadan laipẹ yi.

ni Ipinlẹ Iwọ Orun; Ila Orun Ariwa ati ni Eko paapa tiṣe gba ẹgbẹ na tọwọ tẹsẹ, ti ẹgbẹ Ọlọpẹ na si ṣagbara lati yọ wa kuro ninu isẹ ati ebi.

'Olotu, ṣe ẹnyin na gbọ ikan-ko-jọkan ọrọ ti obinrin ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ kan ti o wa lati ilu Zaria, Malama Ina Nusa sọ fun awọn kan ti o pe ni JUDASI ọmọ ẸGBẸ ỌLỌPẸ? Arabinrin na ni o ya on lẹnu pupọ lati ri wipe awọn ọmọ Yoruba hawa ti Judasi hu si Jesu si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, nwọn si ju silẹ fun awọn ọta rẹ.

Malama Ina Nusa ni, ni Oke Ọya ti on ti wa, awọn Hausa ko jẹ fun awọn ọta kan laye rara wipe nwọn yio ribi ti awọn olori wọn subu bi iru eyi ti nwọn

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Iwa Odale

"Nwọn ni nigbati nwọn bẹrẹsi fi ọrọ we ọrọ lori iṣoro ti o de ba awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ, nṣe ni gbogbo enia njuko ọrọ lu awọn ọmọ Yoruba ti nwọn si npe awọn kan ti nwọn ju ẹgbẹ ọlọpẹ na SILẸ NI ỌDALẸ.

"Oloye Ubani Ukoma, ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ti o wa lati Ipinlẹ Ila Orun ti o sọrọ tẹlẹ Alhaji Adegbenro ko fi ọkan pe kan, nṣe ni o nfi ọrọ gba awọn ọdalẹ ti o salọ kuro ninu ẹgbẹ na nigbati iṣoro de loju.

"O ni awọn ọdalẹ na mọ daju wipe nilẹ Yoruba ni nwọn ti bi Oloye Awolọwọ ti o da ẹgbẹ ọlọpẹ silẹ fun awọn Yoruba, ẹgbẹ na si tanka gbogbo ilẹ Nigeria ti o fi de Oke Okun yẹyẹ ni iyoku, ẹgbẹ na kiṣe ẹgbẹ ti enia le fọwọ yẹ kuro ninu awọn ẹgbẹ oṣelu ni Afirika.

## Iwa Judasi

loye Ukoma tun ṣe Oo bi awọn ??? ọpọ enia

# Awon Ole Dana Lona Lokoja

LỌKỌJA — Oju gbogbo awọn ero ti nwọn nti Okere bọ wa si Ilọkọja ri nkan ninu ọsẹ tokọja yi nigbati awọn ole dana-dana duro de wọn loju ọna ti nwọn bẹrẹ si gba ẹru lọwọ wọn ati gbogbo owo ti nwọn nfi lọ raọja ni Lọkọja.

Akọwe onirohin wa ni awọn ọlọṣa na ko lọ jina, ni arin busọ ti nwa ati mọkanla ni nwọn lọ duro si lati ma ṣe iṣẹ buruku na ti nwọn si fi awọn panu - gorodomu epo mọto dina. Bi awọn dẹrẹba awamọto ba ti de bẹ ni nwọn nduro.

Nwọn ni ti nwọn ba si ti duro ni awọn ọlọṣa na nyọ jade ninu igbo pẹlu ibọn lọwọ wọn, gbogbo wọn ni nwọn fi nkan boju bi awọn ọmọ onigareta.

Awọn danadana na ri ṣẹ, onirohin wa ni owo gidi ti nwọn jagba lọwọ awọn ero ti nwọn nti Onitsha ati Ibadan bọ ju ẹgbẹfa pọnun (£1,200) lọ, awọn ẹru ti nwọn tun ri ko, ko niye.


World's renowned top quality
JAPANESE BICYCLES




Contact your nearest local Bicycle Shop Now!

Mass. Importers, Please Write for Import Information to:

JAPAN BICYCLE TRADE CENTER

P. O. BOX 4117 BEIRUT - LEBANON

# ELETI-OFE

(ANJU WỌN KOSE WI LẸỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS 26, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAMS "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 20670

VOL. XIV. NO 898 SATURDAY Dec 7. - Dec 13, 1963.

## ORO OLOTU:

# Eleyi Na To Ro....

Boya ọrọ Olotu wa ti ọsẹ yi le bi awọn Janma kan ninu, ninu awọn enia ti nwọn nka iwe wa lọsọsẹ; ẹ jọwọ ẹniti a ba fi alaye ẹrọ wa na ṣẹ ki nwọn jọwọ dariji wa. Lori ọrọ awọn Yoruba ti nwọn kọ lati parapọ, ki nwọn fi imọ wọn, ṣọkan ni a nwi.

### Enyin Ara Wa

Nwọn ni nwọn ki pe enia ni ole ki o de ọja ki o ma gbe ọmọ ẹran jọ. Lati ọjọ ti rogbodiyan ti bẹ silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun lọdọ awọn aṣiwaju oṣelu wa, orişirişi SUNA ni awọn ara ita ti nfun awa Yoruba lori ifẹ ara wa ti a ko ni.

Awa ko ba wọn wi, nitotọ bi ara ile ẹni ba fori gba, ti a ko ba mọ ọ ki, ija ni ọrọ na ma nda, bẹ o si dara ki awa alara ma ri ara wa pẹlu alebu ara wa, ki a le tete mọ iru egbogi wo ni a o lo fun arun ti o ba mba wa ja na.

### Yoruba Ko Ni...

Bi ẹ ba ka iwe-lakaye ti ọkan ninu awọn ọkawe wa ti o pe ara rẹ ni ALHERI ỌMỌ HAUSA kọ si wa, ti a tẹ sinu iwe yi loju ewe kẹta, ẹ o ri wipe awa ni enigba ti o pe igba rẹ ni akilaya ti nwọn fi ba ko ile.

Nitotọ ni iwọn ọdun mẹdogun sẹhin nigbati awọn ara wa kan ko ara wọn jọ ti nwọn da ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA silẹ ẹnu atẹ pẹlu abukun ni awọn kan ninu awọn ọmọ Yoruba fi nyọ ebu si ara awọn ti nwọn ṣe akinkanju lati da ẹgbẹ na silẹ. Ko si eebu ti nwọn ko bu awọn aşiwaju ẹgbẹ na tan, tobẹgẹ ti nwọn fi bẹrẹsi gbin igi oro si ọkan awọn Ibo ọrẹ wa wipe awọn Yoruba fẹ le wọn kuro l'Eko ni, bẹ awọn aşiwaju ẹgbẹ Yoruba igbana fẹ fi Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa tun ori ara wa ṣe ni.

### Emi Asape

Diẹ loku, ija igboro fẹrẹ bẹ silẹ nitori gbogbo awọn Ibo ti o wa l'Eko ni nwọn ra ada lati fi ja. Di ọjọ oni ọta ọrọ na si wa larin awọn ọmọ Ibo ati awọn Yoruba ninu ile ti nwọn ngbe ati nibi iṣẹ ti nwọn jẹ nṣe.

Awọn kan ninu awọn aşiwaju ẹgbẹ ibilẹ awọn ọmọ Ibo ni ki awọn Ibo ju wa sile, AWỌN YORUBA KO NI ẸMI-ASAPẸ-iyẹn ni wipe ko ni pẹ rẹ wa, a ko le gbe nkan dori. Njẹ otitọ wa ko ni ọrọ na jẹ loni?

### Afi Igberega

Ko yẹ ki a ba awọn oniwe irohin kan ti awọn nkọwe wọn lati bu ẹnu atẹ lu didapọ ti awọn ẹgbẹ ibilẹ Yoruba fẹ dapọ wi rara, ṣe akukọ awa Yoruba ni a ti fi ogbe ori wa fun kọlọkọlọ yẹ wo. Awa ni a ri bawi.

Bi a ko ba fẹki awọn ọmọ wa ma ṣ'epe fun wa

# Iwe Si Olotu

## Ori Rotimi Pe!

Mo gba fun Lọya Rotimi Williams, baba ẹgbẹ gbogbo awọn Lọya ilẹ Nigeria ti o sọ oju abẹ niko nigbati o mba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ sọrọ ninu ipade nla kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ lọya ṣe lọsẹ ti o koja.

Lọya Rotimi Williams kan abẹ niko fun awọn oṣelu wa ti nwọn lero wipe awọn nikan ni nwọn gbọn lori ofin pajawiri ti nwọn ṣe, ti nwọn ni ki a ma gbẹjọ wa lọsi ọdọ awọn ogunnagbongbo adajọ ni ilu Oyinbo (Privy Council) mọ.

Ẹnikan ki jẹ awa de, nitotọ o dabi ẹni wipe awọn alamojuto eto Ijọba we nyara pupọ ju; awọn nkan miran wa ti o yẹ ki a ṣe bi ọdun marun tabi mẹwa si, ki a to ṣe ọrọ wa ni gedegbe lawa, ọkan ninu awọn nkan na ni ETO KOTU KO-TẸMI-LORUN ti Lọya Williams sọ nipa rẹ yi.

Olotu, Oluwa ma jẹki iru Rotimi Williams tan lori ilẹ wa lailai, eyiti a ba tun ku ki nwọn ma sọ kan awọn oṣelu wa loju.

Emi ni,
Suru—Lere A. Kọlawọle

## Ibosi Awon Olopa Kansulu

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe irohin yin lati kesi awọn kansilọ wa ti a ran lọ si ile igbimọ ibilẹ Eko (Lagos City Council) iwa buruku ti awọn Ọ'ọpa wọn nhu nipa mimu ti nwọn nmu awọn ọmọ wa lọja kakiri, ti nwọn si nti wọn mọle lainidi.

Ọmọde nikan kọ ni awọn Ọlọpa na nmu ti mọle, nwọn nmu awọn abilekọ paapa ti nwọn nkiri ọja lati wa onjẹ ojọ wọn kiri pelu. Gbogbo enia ni nwọn mọ wipe iṣẹ ni oogun iṣẹ.

Wahala ti o tun wa ninu titimọle ti nwọn nti wọn mọle na ni wipe awọn Ọlọpa yi ko ni jẹki awọn ti nwọn le mu yi ranṣẹ si awọn ara ile wọn lati le wa duro fun wọn. Were nwọn a si da wọn si mọto bi ẹran lati lọ ti wọn mọle.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa lọ ibosi awọn ỌLỌPA Kansulu Eko yi ki nwọn ye le awọn obinrin yi mu kiri.

Emi ni,
Eko A. Adeleke

ỌRỌ OLOTU

ni ẹhin ọla, ki nwọn ma fi wa bu lojojumọ o yẹ ki awa Yoruba da ẹgbẹ ibilẹ wa pọ, ki a gbaruku ti ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA nitoripe gbogbo ọmọ Yoruba gba a ọmọ ODUDUWA ni a nṣe.

### Ati Ojukokoro

Ki a ma jẹki ifẹ owo, ilara, anikanjopọn ati igberaga awa-lawa-nibẹ gba ọkan wa, ki a mura ki a ṣe nkan fun orilẹ ede wa ki awọn ọmọ wa le ri wipe a sin wọn debi ti ẹru ko ni ba wọn.

Lẹkansi, a tun kan sara si awọn alagba ti nwọn fẹ dide si ọrọ na, ki nwọn majẹ ki o rẹ wọn nitoripe agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun pa. Alajọbi yio gbe yin, Oduduwa yio ṣe atilẹhin fun gbogbo wa. Eleyi na to ero fun wa.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

## £25,000 Owo-Obi

Emi Ayiluka tun de o !'ọrọ mi dori k o dori, o dori awọn oṣelu kan ti riba owo-ijoko agba ti nwọn fẹ gba lọwọ awọn Oyinbo ajoji kan ha lọrun. Mo gbọ wipe owo na kiṣe ọmọde owo-ọkẹ kan o le ẹgbẹ-dẹgbẹn pọnun (£25,000) ni nwọn sọ wipe awọn fẹ gba lowe awọn Oyinbo na ti .nwọn ba fẹ mu iṣẹ wa fun awọn ọmọ wa lati ṣe.

Mo gbọ wipe awọn Oyinbo ajoji na salọ bamu-bamu, nwọn ni a nrọju jẹkọ ọbun, ọbun tun npan ẹkọ rẹ kere ni ọrọ wa nilẹ Nigeria yi. Emi Ayiluka gbọ wipe awọn ọlọpa nṣe iwadi ọrọ awọn baba oṣelu ti awọn FẸ GBA RIBA"na lọwọ, kinni nwọn yio ri ni bẹ ? Omi-ẹkọ ni gbogbo rẹ.

## Baba Onitolotolo Nko ?

Bi a ba fẹ ki awọn araiye ri wipe ọwọ wa mọ, o yẹ ki a ṣe iwadi ile iṣẹ ẹgbẹ-jẹda gbogbo ti Ijọba Apapọṣe da silẹ, awọn ile iṣẹ bi ti awọn ọlọkọ-ilẹ (railway), awọn alaropileni (Airways) ati ti awọn oni ina - mọnamọna (ECN). Mo gbọ wipe riba ati ojusaju ti fọ awọn kan lori nibi iṣẹ wọnyi, Bi ko ba nṣe bẹni kinni ṣa Baba kan de ibiti o fi nsin tolotolo bi igba, adiẹ bi iriwo, aguntan bi ọgọrun ati apoti ọti bia (beer) bi ti hoteli ni Ikẹja?

## Riba Ikoyi Da ?

Ti BABA ONITOLOTOLO NI IKẸJA ni a ri ti a nwi, ti BABA Ikoyi nkọ pẹlu ijẹkuiẹ ? Bi BALEWA Tafawa Balewa ba fẹ ṣe ọrọ na ni ire, o yẹ ki o jẹki a ṣe iwadi ẹnkuari gbogbo wọn patapata, tabi eti on alara paapa bi i kun?

## Baba Elelede Nko?

Ẹnyin ara mi ti awọn Baba Onitolotolo ni ẹ ti gbọ yen, ẹ si tun gbọ waka awọn Baba oniriba ni Ikoyi, awọn ONIRIBA BABA Ẹlẹlede ti Enugu mọ Port-Harcourt nkọ ? Mo gbọ wipe awọn ti o ngba owo ẹhin ni Ipinlẹ Ila Orun ni ilu awọn Ibo mọ ọna ti nwọn ngba fi gba owo riba ti nwọn. Nwọn ni baba alarina ti o mba wọn gba a.

Bi o ba nfẹ ipo ọga nibi iṣẹ ninu ki o mu EGO (owo lo njẹ bẹ) wa tabi ki o fun ọga-agba ni ẹran ewure, ẹran ẹlẹdẹ pẹlu akọ aja ati akeregbe oguro mẹfa (MAYIN ni wọn npe ẹmu ogu-nilu Ibo) wa sile ọga, ki o si ko gbogbo nkan wọnyi si nu ogba ọga.

## Oyinbo Mo

Awe, nkan mbẹ nilu Nigeria ti a wa yi o. Idi rẹ niyi ti ko fi si iṣẹ ati owo larin ilu; gbogbo awọn oniṣẹ awadu (miners) ni nwọn nda duro ni Enugun, awọn ti Iogunlogo tiṣẹ ti nwọn nkọ awọn ọmọ lẹkọ lugbẹ; ọpọlọpọ awọn Oyinbo Oniṣowo paapa ni nwọn nwa ọna ti awọn yio gba kuro nilu yi salọ si ilu wọn; kinni faa ? Riba pẹlu ijẹkuje ni ọrẹ mi. E ba wa so fun Ọlọla Tafawa Balewa, Olotu ijọba ilu yi ki o jẹki a yẹ gbogbo idi ile iṣẹ Ijọba wa wo. Awọn enia ti nwọn nhuwa bi ole, bi ole pọ nina iṣẹ Ijọba wa.

## Iku D'epinni

Gbogbo awọn ara ilu Nigeria, Imale ati awọn Kiriyo ni awọn ni igbagbọ wipe bi ọdun tuntun ba fẹ wọle, ọdun ti o nlọ a ma fẹ mu ọpọlọpọ enia lọ lọwọ lọwọ nipa iku; lati bi oṣu meji sẹhin, orisirisi ọfọ ti o kanilara ni a ngbọ, ọkan ninu wọn ni ọmọdebinrin kan ọmọ Imale ti nwọn npe ni ESU LEMỌMU, ọmọ ọmọ Lemọmu atijọ ni ilu Eko ti o jalaisi ni ile wọn lati Mọshalasi Jimọ laipẹyi. Gbogbo awọn ọmọ Eko ti nwọn wa l'Oke Ọya a niran igbati Ologbe Esu nṣowo diẹdiẹ lati ilu Hausa wa s'Eko, o si jẹ ẹniti o g'ajumọ larin awọn ọlọkọ-ilẹ. Esu, ọrun re!

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

THE ANSWER TO TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED AFTER SALES SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA, ONITSHA.

*Sub - Distributors :—*

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.

# Meet The New President Of America: Lyndon B. Johnson

Lyndon B. Johnson, the new President of the United States, as was his predecessor John F. Kennedy, has been a warm supporter of African independence and economic progress.

He was born on August 27 1908, gained B.Sc.; degree in a state Teachers' College and was a teacher for several year in public schools.

## Vice President

Mr Johnson, Vice President under Mr. Kennedy, became the the nation's 36th Chief of State on November 22 when President Kennedy was felled by an assassin's bullet in Dallas, Texas.

Duringt he Kennedy Administration, Mr. Johnson had an opportunity to meet with a number of African leaders while they were in the United States. On some occasions, he acted as Mr. Kennedy's personal greeter in Welcoming distinguished visitors to Washington. He attended most state luncheons and dinners for distinguished African leaders at the White House and met with many of them in his office.

## Africa's Friend

He went to Africa in April of 1961 as President Kennedy's personal representative to Senegal's independence celeberations. The visit was recognized as a mark of the Kennedy Administration's keen interest in Africa.

Mr. Johnson's views on Africa can be summed up in a statement he made two years ago while greeting a visitor from Africa:

"It is not only to our interest but it is our desire that the young African nations have the economic health that will enable them to live not only in dignity but in proud independence . . .

" We have spent so many decades in winning the wilderness and pushing back the physical frontier that we have not lost our sense of adventure – our pleasure over the launching of a new nation. In the last few years new nation after new nation has been launched in the Great Continental of Afric. . .'

" The Sleeping child has risen from the slumber of centuries and is stepping bodly in the 20th century. Because we remember our birth pangs we are more than anxious and eager to extend the helping hand of coopration.

"We in America welcome our new neighbors in Africa. We wish them well. We rejoice when they flourish and share their happiness in a bright future."

Mr Johnson wrs accorded a tremendous welcome in Senegal and he assured the people that the United States hopes for "very friendly and mutually beneficial relation" with all the African nations.

Independence, he stressed, "is not an end in itself but a means to prove the lot and enlarge the opportunities for all the people."

The United States, Mr Johnson declared, felt a kinship for the African nations because "we walked this road of independence ourselves."

As he travelled about Senegal, Mr Johnson sa'd he saw in the 'eyes of the people an expression of genuine friendship toward America and a desire to build up their country dignity, peace and justice for all."

### MET BALEWA

Nigerian Prime Minister Balewa visited the United States in mid-1961 and Vice President Johnson represented President Kennedy at the airport arrival ceremony. He told the Prime Minisiter :

"You will find as you travel through this country a deep interest in the exciting developments which are taking place in Africa today with the formation of new, self-governing, independent states.

"This is one of the most significant events of modern times."

# Olofintoto Ni

(O bere loju ewe keta)

ti Oloye Awolowo subu yakata yi. O ni tani o tobe ninu awon Ibo? Awon Ibo ni Ipinle Ila Orun ko je fi awon enia won sile rara. Kinni o wa fa ti awon Yoruba wonyi?

## Talaka Parapo

'Olotu, eniti o ba wa si ibi ipade nla na ni o le gbo pato oro awon odale ile Yoruba na ti Ogbeni kan, Ahmed Pategi ti o wa lati ilu Tapa so pelu Iya-afin Brown ti o wa lati Bonny ni Ipinle Ila Orun ni agbegbe Port-Harcourt.

Se enyin na wa ri wipe oro ti mo so fun awon omo Yoruba nijosi wipe awa Hausa kise odale, oro pataki ni?

'Ni oju mi o babi enipe awon talaka inu egbe Olope (AG) parapo nitoribe ninu ipade nla kesan ti nwon se yi a ko ri awon baba onikun nla pelu oto domi-domi nibe, gbogbo won ti ba igba lo bamu-bamu. Mo gbo wipe ikun opolopo awon ti nwon salo na ni o ti fa bi odo. Boya awon talaka fe be saiye titun ni ami yi je.

Emi ni tiyin,
Alheri omo Hausa "

Oro re enyin ara wa! E ka ORO OLOTU loju ewe Karun iwe yi lori ALHERI yi.

# Baba Ologogoro Fi Ogorun Ponun Tanran

IJEBU—ODE — Adajo Kotu awon olopa ni ki baba ologogoro kan, ara Ilaje ti oruko re 'nje Rufus Ojubuyi ti nwon ba garawa oti ogogoro marunleladota lowo re, ni ki o lo fi ogorun ponun (£100) tanran. Nigbati nwon pe ejo odaran na, o ni ki nwon ma se wahala rara; on jebi oro na.

Oga olopa ti o mu odaran na so fun adajo bi awon ti se nse ise kiri ni ojo kan, ti awon ba odaran yi pade larin agbami rsa, ti nwon ko garawa oti ogogoro sinu oko won. Olopa na ni nigbati awon da won duro lati ye oru won wo, nwon ni epo ni awon di sibe.

da epo sori gbogbo awon garawa na, a je wayo ni gbogbo re, oti dugbolugi ni nwon ro sibe.

Awon olopa ni ti nwon ba fe ta gbogbo oti na a to egbeje ponun (£1,400) sarai.

Baba Ilaje na ni on fe ta awon garawa oti na fun [illegible]

Nitoto, awon ri ti nwon Keresimesi ni;

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

# International Court Decision On Cameroons Complaint

LONDON—The International Court of Justice ruled on Monday, December 2, that the ending of the British Trusteeship over the Cameroons and the joining of the Northern Cameroons to Nigeria were not acts by Britain but the result of actions of the United Nations General Assembly.

The International Court ruled that it would not adjudicate on the Cameroon Republic's complaints about Britain's administration of the Cameroons Trust Territory and, in particular, about the conduct of the 1961 plebiscite there.

The plebiscite asked the people of the Northern and Southern Cameroons whether they wished to become independent by joining the former French Trust Territory of Cameroun or joining Nigeria. The people of the Northern Cameroons voted to join Nigeria and the people of the Southern Cameroons voted to join Cameroun (which, like Nigeria, had become independent in 1960).

The United Nations General Assembly later endorsed the result of the plebiscite, considered that the people of the two parts of the territory had freely and secretly expressed their wishes, and decided that Trusteeship Agreement placing the Northern Cameroons under British administration should end on June 1, 1961.

The International Court ruled that the Cameroun Republic could no longer ask it to adjudicate on this question. The ending of the Trusteeship Agreement and the joining of the Northern Cameroons to Nigeria "were not the acts of United Kingdom but the resuls of actons of the United Nations General Assembly." It was the Assembly which had decided to end the Trusteeship Agreement.

## Duke Of Edinburgh To Represent Queen

LONDON — The Duke of Edinburgh will represent the Queen at tee independence celebrations in Zanziber and Kenya next week. The following anouncement was made by Buckingham Palace yesterday, Monday "The Queen, at the request of tee Prime Ministers of Zanziber and of Kenya, has invited H.R.H. the Duke of Edinburgh to visit Zanziber and Kenya as Her Majesty's Special Representative at the Zanziber and Kenya Independence Celebrations. His Royal Highness has accepted with much pleasure"

Zanzibar is to proclaim its independence on December 10 and Kenya on December 12.

It is understood that the Duke expects to leave Britain by air on Sunday December 8, arriving at Zanzibar the following evening.

He will leave Zanziber for Nairobi after the celebration on December 12.

The Duke was last in Kenya with the Queen in February, 1952.

## Read and Advertise in Eleti-Ọfẹ Weekly.

## Churchill Celebrates 89th Birthday



LONDON...Rt Hon. Winston Churchill, oldest statesman in England celebrated his 89th birthday on Saturday November 30 last week in his country home. Former Prime Minister Sir Winston, as Home Secretary introduced Prison Reforms into Great Britain in 1910. He recently resigned from active politics early this year.

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

**Ayiluka Ni:**

## Nusi Agboola Jalaisi

(O bẹrẹ loju ewe karun

Ọrọ awọn ọmọ Yoruba onişowo ti nwọn ti ba awọn Hausa şowo ni nigbati aiye roju jẹki nniran iya wa kan ti o jalaisi ninu ọsẹ ti o kọja yi ni ọna Ikorodu ninu ile rẹ. Agboọla tişe iya Ọgbeni Rafiu Balogun ọmọ Ologbe Alhaji Balogun ni ita Balogun l'Eko.

Ologbe Nusiratu Agboọla jẹ ọmọ "BABA ỌLỌMỌWẸWẸ" Ologbe Agboọla ni Ikereku ati ni Ijaiye ni Abẹokuta. Ologbe Nusiratu jẹ onişowo ti o fi ọdun gbọrọ gbe Jos ati Kano ki o to şẹşẹ wa sinmi lọdọ ọmọ rẹ, Rafiu ti o nşişẹ lọdọ awọn Oyinbo A G Leventis ni Iddo. Emi Ayiluka ki awọn ẹbi Ologbe na, awọn bi Oloye Olnokun Lawale ni Ijaiye, Ọgbẹni Shitta Agboọla, Alhaja Adikatu Agboọla ati awọn bẹẹbẹ ku asẹhinde.

## Mobo Iya Alawo

Ọfọ nla kan ti o tun şẹ l'Eko Arin l'Eko laipẹyi ni ti Iya-Afin Mọbọ Plumpter (ọmọ Ọshọ) Iya Alawo Tanganran ni Oke-Arin. Ọmọ Ẹgba ni Mọbọ Ologbe na, o si ş'enia pupọ. Mo ki awọn aburo rẹ mejeji ati awọn ẹbi Ọshọ, nwọn kụ afẹku; ọjọ yio jinna si ara wọn. Şe ẹnyin na wa ri wipe nitotọ ni iku di meji epinni.

## Olotu Ilu Dahomey

Mo gbọ wipe baba jagunjagun Olokun mẹta, Ọgbẹni Christopher Sogbo ti o nse Olotu Ijọba fidihe ilu Dahomey ti fi kele gbe ọrẹ rẹ, Hubert Maga ti o ti nse balẹ Olori gbogbo awọn alamojuto eto Ijọba Dahomey, nwọn ti ka niwe ihamọle wipe ko gbọdọ jade sode. Ọbọ ala ogun irun ni ko jẹki a mọ.

## Awon Olopa Nse Iwadi Bawo Ni Iwe Idanwo se Han sita

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Awọn oga ti nwọn nşişe ninu ile ti nwọn ti nşe eto ẹkọ ni awọn iwe kan ti awọn ri gba lọwọ awọn kan lati Eko ati nibomiran ni Ipinlẹ Iwọ Orun, wipe gbogbo iwe idanwo ti awọn fẹ fi dan awọn ọmọ wo ni awọn ti nri lẹwọ wọn kakiri, ni o jẹki awọn sọ fun awọn ọlọpa wipe ki nwọn ma wa awọn ọmọ na kiri.

Ọrọ na ko ti ye wa si nitoripe awọn Ọlọpa ko ti awọn enia mu sako ju ọmọ ilewe giga Kings College ti nwọn ri ẹyọ iwe idanwo ẹkọ inu Bibeli kan lọwọ rẹ lọ.

Ni ilu Enugu ni a tun gbọ wipe awọn Ọlọpa ri tisa kan ti o wa ba ọrẹ rẹ ti awọn jọ nşe işẹ tişa gbamu nibiti o gbe ti mba a kọwe idanwo rẹ lọwọ Ọrẹ rẹ tişa ti o ni lati şe idanwo yi fun ara rẹ paapa joko sile. Awọn enia kan ni owo nla ni tişa na san fun ọrẹ rẹ na ki o wa ba şe idanwo yi.

---

## Obinrin Pansaga

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

ju awọn oşu mẹsan fun irọ ti o pa fun awọn ọlọpa nigbati nwọn nşe ẹjọ ọkunrin kan ti nwọn npe ni "Lucky" Gordon ni ilu Oyinbo.

Adajọ na ni on şe anu rẹ şugbọn ki o lọ şe ọdun Keresimesi lọgba ẹwọn.

# Awon Aguda Da Tisa Duro

(o bere loju ewe kinni)

Awọn opitan Aguda ni Pope Paul yini yio jẹ Pope kini lati nkan bi ẹgba ọdun, ni aiye Peter ti yio kọ fi ilu Rome silẹ lọ si Jerusalemu.

Ninu wipe Papa Mimọ nmura lọwọ lati lo si ilu mimọ ni a gbọ wipe awọn Alufa Padi nda awọn tişa ti nwọn nkọ awọn ọmọ lẹkọ duro ni gbogbo agbe gbe Onitsha n Ipinlẹ Ila Orun.

Akọwe onirohin wa ni awọn Aguda nikan kọ ni o nda awọn tişa wọn duro nilu awọn Ibo, o si awọn Ijọ Angilika (CMS) paapa da gunlọgọ awọn tişa wọn dupo. A tun gbọ wipe ọpọlọpọ awọn tisa na ni awọn ko ri owo san owo oşu fun. Nwọn ni o ju ẹgba marun pọnun (£10,000) lọ ti Ijọba Ipinlẹ na jẹ ni gbese owo oşu ti nwọn ni lati fun awọn Ijọ CMS., a ko tiłẹ le sọ ti awọn Aguda ati Methodist.

# Olola Dokita Azikiwe Tajo De



Dokita Nnamdi Azikiwe, Olori Ijọba ilẹ Nigeria ti o ti nşe abẹwo ilu kakiri oke Ọya lati bi ọsẹ mẹta wa yio pada si Eko ni ọjọrọ oni. Ọkọ oju omi ti Ijọba ti nwọn npe orukọ rẹ ni Valiant ni yio wọ gunlẹ ni Idumagbo ni ọjọrọ oni ni de de agogo mẹrin abọ. A gbọ wipe ki Ọlọla Azikiwe to kuro ninu ọkọ na yio ba gbogbo awọn akọwe oniwe irohin sọrọ gbogbo nkan ti on ri ni irin ajo na.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos
Phone 23370; Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box 467